# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VLO XIV NO 884 LAGOS SATURDAY AUGUST 31—SEPTEMBER 6 KỌBỌ MEJI (2D) 1963


### Omi Goke Mapo, Odogun Goke Alo:

# Ogunpa Se Onile-Mole, Ilu Ibadan Di Omilewonde

IBADAN—Gbogbo awọn ti nwọn ka itan ikun omi ti igba Noa ninu iwe Bibeli ti nwọn ko mọ bi omi na tiṣe bẹrẹ ni nwọn mọ ni Ibadan ni ijẹta nigbati ojo kan rọ titi ti ko da, ti agbara omi bẹrẹsi ya wọle. Ere ni, awada ni, omi odo Ogunpa si ti ya wọ gbogbo ṣọbu ti nwọn nta ọja

Ẹnikan ninu awọn akọwe-onirohin wa ti ọrọ ikun omi naṣe oju rẹ ni Ibadadn lọjọrọ ijẹta ni irohin ko to afojuba ni ọrọ na. O ni Orile Ilugun ni awọn ti kan ọwọ oju na leti iyana Olokemeji. O ni diẹ ni eyiti awọn ri ni Ilugun, ojo ti Tesan Adio peleke, gbogbo oju irin ọna ọkọ reluwe ni omi agbara kun ti omi si ya si arin abule ti nwọn npe ni ỌMI.

Gbogbo awọn mọto ayọkẹlẹ ti ko ni ẹmi ikun omi ni nwọn doku soju ọna titi ti nwọn ko le lọ si bi kan mọ. Nwọn ko ṣe wọ, nwọn ko si ṣe ti sapa kan nitoripe iṣan omi agbara na le pupọ, o si le gbe enia lọ. Gbogbo awọn oni mọto akero ati akẹru wa nra bi ajapa titi ti o fi de Apata-Ganga: Omi agbara ti bo ori afara ti o wa ni Oko-Ọba ti nwọn npe ni Moor Plantation.

Agbara kaka ni a fi kọja nibẹ. Onirohin wa ni nigbati awọn de Gbagi ti awọn fẹ gba ṣọbu SCOA wọ Ogunpa, ọna ko ṣe gba rara, awọn yi pada gba Amunigun nigbati awọn yọ


(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


## Awon Ara Ibadan Ko Ri omi Dara-dara Mu Mo

IBADAN—Lati ana ni awọn alamojuto ẹrọ afami ilu Ibadan ti nkegbe lemọ lemọ wipe ojo ti ba ẹrọ afami ilu na jẹ nitorina awọn ara Ibadan ko ni ri omi-ẹrọ ti ko ni kokoro ninu mu fun bi ọsẹ meji gbako.

Nwọn ni omikomi ti nwọn ba ri pọn yala ninu kanga tabi lodo ni ki nwọn ma ṣe wọn lori ina fun iṣẹju mẹdogun ki kokoro ti o le ko arun ba wọn ba le ku patapata.

Gẹgẹbi ẹ ti mọ ko si omi odo ti o mọ gara tobẹ ni Ibadan, a fi awọn omi agbara GẸGẸ ati Kudẹti mọ Ogunpa; Omi odo Ẹlẹyẹle ti nwọn ko ba si ma ti lo ni a gbọ wipe ko si ọna lati mu mọto lọ si idi rẹ yi.

A gbọ wipe ile iwosan awọn alaisan ti ó soro pẹlu awọn ile awọn akẹkọ ni awọn alamojuto omi-ẹrọ ti fọwọ sọya fun wipe awọn a gbe mọto lọ si Iwo ati Oshogbo lati lọ pọnmi fun wọn.

### Layi S'eke Layi Jale:

# Ijoba Eko Gbejo Fun Oyinbo Onise Won

EKO—Oyinbo kan ti o njẹ George Innes, ẹni ọdun mẹrinlelọgbọn, ọga ile iṣẹ ẹrọ alaworan (Nigerian Television) ti Ijọba Apapọṣe gba senu iṣẹ ni OKUN ALASIA ni a gbọ wipe nwọn da duro ni idaduro iwọsi, nwọn si ni ki o palẹ ẹru rẹ mọ ni kiakia ki o kuro nilu

Oyinbo na ni on ko mọ nkan ti on ṣe, o ni hoya iwe owo inakuna kan ti awọn kan ni ki on tọwọ bọ, ti on kọjala ni o fa idaduro na ko ye on rara,

O ni on niran wipe awọn enia kan gbe iwe ẹgbaa pọnun (£2,000) kan wa si iwaju on wipe ki on fọwọ si i ki nwọn le san fun Oyinbo ọga Tiger ẹl ṣẹ fun aworan televisiōn ti nwọn gba nibi ere-ẹṣẹ na ni Ibadan Ọgbẹni Innes ni on kọjale. O ni orișirișị iwa buruku ni o nlọ labẹlẹ nibi iṣẹ awọn na ti on fẹ ki 'Ijọba ṣe ẹnkuari le lori ki nwọn ba ma jin sofin rara.

Oyinbo na ni ki awọn alamojuto Ijọba Eko jọwọ ki nwọn fun on ni aye diẹ si ki on le waye palẹ on daradara. O ni gbogbo ọja ti on ra lawin wa nilẹ, o ni awọn bi mọto ayọkẹlẹ ati ọkọ oju-omi ti on ra fun awọn ọmọ on wa nibẹ on ko kuku le ru wọn lọ silu Oyinbo, on ni lati wa enia ti yio ra wọn ni.

A gbọ loru ana wipe nwọn yọnda ijọba ẹjẹ fun un wipe ko fi ṣeto awọn ẹru rẹ na ti o fẹ pamọ. Nkan mbẹ ninu ọrọ wọn na.

# Olopa Mba Bale To'ba Awon Egba Jagun Rojo Apania

IBADAN—Awọn ọlọpa mba Sanusi Alaka, Bale abule Mokore lẹba Ibadan, ti o pasẹ fun awọn ara ilu ba rẹ wipe ki nwọn pa awọn Ẹgba ti o mba awọn du ilẹ, ro ẹjọ apania, on pẹlu Gabriel Fadairo, Lamidi Akinji, Busari Adelani, Joseph Ayoọla, Taiwo Ogunyẹmi, Lamidi Alade, Yesufu Arẹmu ati Alani Alade. gbogbo wọn ni awọn ọlọpa mba rojọ apania.

Eni meji ninu awọn ara abule wọn ti ọrọ na soju rẹ ni nwọn sẹsẹ rojọ ni iwaju adajọ Kotu awọn ọlọpa ti o si ngbọrọ na ni oi yio ba di nkan ti nwọn yio gbe lọ si Kotu ti nwọn ti ndajọ awọn apania ni kotu gaaran.

Ẹri awọn ọlọpa ti o kọ rojọ ni Ọgbẹni Yẹkini Folọrunsọ ti o ngbe abulu Mokore na. O ni nitotọ ni awọn Ẹgba alabagbe awọn ti nwọn nroko ni abule awọn ti fi igba kan pe awọn lẹjọ nipa ala ilẹ oko kan awọn nja si: O ni awọn Ẹgba ni adajọ da lare wipe awọn ni nwọn ni ilẹ ti awọn nja lelori si na

(Wo iyoku loju ewe kẹfa)

## Baba Alhaji Adegbenro Jalasi

ABẸOKUTA—Sanni Adegbenro, Balogun awọn Imale ni Owowo leu Alẹokuta jalasi ni ijẹrin ọjọ Iṣẹgun. Oloye Adegbenro ti o jalaisi na ni o bi Alhaji D. S. Adegbenro, igbakeji olori awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG). Ẹni ọdun marundinlọgọrin ni, Ni Calabar ni Alhaji Adegbenro paapa wa ni ibiti o gbe ti npolowo idibo fun awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ki o to gbọ wipe baba on jalasi. Wa rawere ooti gun ọkọ arọpleni wa pada sile fun sinku baba rẹ na ti nwọn işe ni ana ọjọ Jimọ ni Agọ-Owu, Abẹokuta.

Ibi isinku na dun pupọ, gbogbo awọn Imale igun mẹrẹrin ilu Ẹgba ni nwọn pe sibẹ şiba şiba. Awọn ọmọloku si na wabiwọsi owo fun gbogbo awọn ti o wa si ibi isinku na lati Ibadan ati Eko.

---

E ka oro **OLOFINTOTO** Eleti-Ofe ati awon Oniwayo (Pools) loju ewe keta iwe yi. **OLOFINTOTO** ti tuna asiri won. Eleti—Ofe d'araba e ma ka a nigbagbogbo.

---



# Mo Le Gbe e!

Aworan ti e nwo yi ni ero ti nwon fi ngbe eru sinu oko oju omi. Bi o ti wu ki eru na wuwo to ero yi le gbe e. Awon Oyinbo elero kan ni o sese se eleyi fun tita, nwon ni o dara ko ni baje fun odun marun tabi odun meje. Awon alamojuto Ijoba Nigeria ti f'iwe sowo si awon Oyinbo ti o nta a, wipe awon fe mejila ninu ero agberu na.

## Olofintoto Tu Asiri

# Awon Ole Oniwayo Onipulu (Pools) Ilu Nigeria Patapata

Boya ẹ ko mọ ibiti awọn ole baba oniwayo onişẹ pulu (football pools) wa? Nwọn pọ ni Mushin ati Ibadan awọn ọmọ işẹ wọn si wa pọ jaburata ni ilu Eko nibi, Bi nwọn ti nnawo iyebiye lati fi polowo ọja pulu wọn ninu iwe irohin ni ọsọsẹ ni nwọn nṣe iwe ipinka fun awọn ti nwọn fẹ parọ ni gidi.

Ninu ọrọ wosika mi ọsẹ yi, emi OLOFINTOTO Eleti-Ọfẹ yio tuna aşiri bi awọn baba oniwayo na ti nfi ọna ọgbọn arekereke gba owo iyebiye lọwọ ẹnyin ara ilu fun yin ni ẹkunrẹrẹ.

### Ofin Pulu

O to iwọn nkan bi ọdun mẹta nisisiyi ti Ijọba Apapọşe gbe ofin pulu (football pools) jade wipe ẹnikẹni ni ilẹ Nigeria ko gbọdọ fowo sọwọ si ilu Oyinbo mọ fun atita orire pulu yi mọ. Awọn alamojuto Ijọba wa ni awọn şe eyi nitoripe owo wa ti o njadẹ lọ si ilu okere pọ ju, nwọn ko mọ wipe ọna ole ni nwọn nsan fun awọn baba oniwayo ti o wa ni Mushin, Eko, Ibadan ati Aba:

Nitotọ ni gbogbọ awa ara ilu Nigeria ti fi igbakan fọkan si owo gọbọyi ti awọn enia njẹ nilu Oyinbo lori orire pulu yi, şugbọn ẹniti ko ba gba ami mẹrinlelogun (24 points) ko le gba ipin owo ti o jọju rara. Nitori eyi olukuluku awọn ti o nta orire pulu ma njijadu lati le ri wipe awọn le pa ami mẹrinlelogun (24 pts) yi ni gidi.

### Wayo De!

Gbogbo ọdun ti a mba awọn Oyinbo onipulu ta pulu ni ilu Liverpool, Cardiff ati London boya ni a ri to enia mejila ninu awọn ara Nigeria ti o gba ami mẹrinlelogun (24 pts) ti nwọn nwa na.

Şugbọn kete ti awọn aşofin ilu wa ti şe ofin wipe pulu tilẹ wa ni ki a ma şe ni wayo ti bẹrẹ. Ọsẹsẹ ni awọn baba oni wayo onişẹ pulu na nri ẹniti *o* şe orire, ti o ri gbogbo ami mẹrinlelogun tan.

Boya ẹnyin ọkawe mi ko mọ bi awọn oni wayo onişẹ pulu yi ti nşe e. Bayi ni ọna ti nwọn ngba şe wayo na. Ti nwọn ba ti ri gbogbo, owo ti a da jọ fun wọn tan ni ọjọ SATIDE, awọn baba oniwayo yi a yọ ọkan silẹ fun ara wọn eyiti nwọn npin na ko nşe owo kekere, nigba miran irinwo pọnun (£400) nigba miran awọn ọga yi npin ẹdẹgbẹta pọnun (£500); bi nwọn ba ti pa owo to ni ọsẹ ni i nwọn ji npin apasapọ na. Iyẹn bẹ.

### Amulumala

Nipati Amulumala iyẹn ko ni onka rara. Bayi ni awọn oniwayo yi şe nşe amulumala wọn .Ti o b ti di alẹ ọjọ Satide ti nwọn ba ti mọ ibi awọn e'ere bọlu tişe gba a si (foot-ball results) ni ilu Oyinbo nwọn a yara sare fi oruko oloruko tabi ọrẹ wọn ta iwe pulu (coupon)

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# Omolewe T'oloyun Pokunso Ni Yara

AWKA—Anu abiyamọ şe gbogbo awọn ena ti o ri oku ọmọdebinrin ọmọ ilewe kan ẹni ọdun mẹriudinlogun ti orukọ rẹ njẹ Ogbone Nwokoye ti o pokunso ninu iyara awọn obi rẹ nigbati awọn ọlọpa ru okurẹ jade.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa ọmọdebinrin na, ninu ọdun ti o kọja ni awọn obi rẹ jalaisi, eleyi ko si le jẹ ki o ma ba ẹkọ rẹ lọ mọ. Lọjọ ti nkan yi şẹlẹ, awọn aladugbo ni awọn ri ni alẹ ki o to wọle sun.

Nigbati o di owurọ awọn ko ri ọmọbinrin ko ji bọ sita bi o ti ma nşe, awọn ẹbi rẹ wa ya ilẹkun iyara wọle nibẹ ni nwọn ri oku rẹ ti o nmi dorodoro loke nibiti o gbe pokunso si.

Wara were nwọn ti lọ kesi awọn ọlọpa. Nigbati awọn ọlọpa wọ iyara na, nwọn ri iwe akọle ti ọmọ na kọ wipe on ni on pa ara on nitori oyun oşu mẹta ti on ni, ti ẹniti o fun on loyun na kọọ si on lọwọ ti o salọ.

Ko si iya, ko si si baba, tani on tun ni ti yio şe ajo on? Bi on ba kuku ku, on a lọ sinmi kuro ninu wahala aiye yi.



Awọn Elere bọlu afẹsẹ gba ti ilu Oyinbo ti nwọn fi nko wa lowo lọ niyi.

# ELETI—OFE
(A NJU WỌN KOSE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL.XIV.NO 884 SATURDAY AUG 31 - SEPTEMBER 6 1963


## Adamodi "Olopa" Lo Sewon Odun Marun

YABA—Baba kan Emanuel Seriki ti o ni iṣẹ ọtẹlẹmuyen ni on nṣe fun ọga awọn ọlọpa ni adajọ-agba, Ogbeni F. S. Ogunmuyiwa sọ sẹwọn ni ọsẹ ti o koja lori ẹsun wipe o pe ara rẹ ni ọlọpa fun dẹreba awamọto kan ti oruko rẹ njẹ Adisa Buraimọ laipẹ yi.

Awọn ọlọpa sọ fun adajọ ni kotu bi ọrọ na ti ri bayi: nwọn ni lọjọ ti Buraimọ dẹreba yi nfi mọto awọn Oyinbo re keru lọ si Ibadan, o ri ọdaran Seriki yi ni Iperu, o wọ mọto ti o fi nkeru lọ na.

Bi nwọn ti lọ lọna ni ọkuurin ọdaran na gbe igbaju e dẹreba na loju, o ni on nmuu loni, ti ko ba fẹ ki on tuna aṣiri rẹ fun awọn Oyinbo onisiga, Nigerian Tobacco Company ti o gba siṣẹ wipe nṣe lo nfi mọto wọn kero lọna ki o yara mu pọnun mẹwa wa ni kiakia.

Dẹreba na ni nigbati o ri ọga ọlọpa ni on ni on ba yara ko pọnun mẹta ati ṣile meje ti o wa lọwọ on fun un, o ni on si tun jowe ile ti on gbe fun un ni Ọreofẹ ni Surulere wipe ki o wa gba iyoku ti on ba padu de Eko.

Iyawo Buraimọ dẹreba na ni lọjọ kan ni on ri ọdaran na ti o wọle wa ba awọn ti o ni on fẹ gba owo iyoku lọwọ bale on.

Iyawo yi ni on yara ran ọmọ on obinrin ti o wa lẹkule wipe ki o tete lọ pe ọlọpa wa.

Nigbati ọlọpa de ni nwọn ba mu ọdaran na lọ si tesan wọn. Ninu ẹjọ ti ọdaran yi ro fun adajọ, o ni irọ ni nwọn pa mọ on, o ni on ko fi igba kan gba owo kankan lọwọ dẹreba na rara. O ni nigbati o sọrọ rẹ loju ọga awọn ọlọpa ti on njẹ John Lynn, o ni on ni fun on laṣẹ wipe ki on mọ wa idi ọmọ dẹreba na kiri. Ofofo yẹn ni on fi wadi lọ sile rẹ ki nwọn to mu on wipe on wa gbowo ni.

## Ẹjọ Kola Eleri Sonu larin Ilu Eleyi Ara

ENUGU—Ọrọ bẹhin yọ nilu Enugun! Ọjọ lati ro ẹjọ ku ọla, awọn ara ilẹ wa eleri ni awati, kasa nkan se! ni igbe ti gbogbo awọn enia ti o gbọ wipe Ọgbẹni kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni David Briggs, ti awọn ọlọpa gbojule wipe on ni yio tuna aṣiri awọn ako e ti nwọn ti nji epo mọto ijọba ko ni nibi iṣẹ, fun adajọ ti o nṣe ẹjọ wọn, sọnu ti nwọn ko si ri i mọ.

(Wo iyoku ni oju ewe Kẹjọ)

# Iwe Si Olotu

## Awon Ti O Ku Si Mosalasi . . .

Olotu, ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati bere idi ọrọ yi ti o ndun mi ninu yi lọwọ awọn ọkawe yi boya mo le ri awọn ti o le la die fun mi nipa nkan na ti oru mi loju nitoripe nkan iruju pọ pupọ ninu aiye ti a wa yi.

Ọrọ ti o nru mi loju ti mo fẹ wa idi rẹ na niyi: A ngbọ lọdọ awọn oniwasu ati oniwasi wa lojojumọ wipe ẹnikeni ti ko ba lọ ṣe isin ni Ṣọṣi ati ni Mọsalasi igbagbọ tabi ẹsin ti o fi nsin Ọlọrun rẹ ko pe rara.

Ninu ọdun yi ni a gbọ irohin meji ti o yani lẹnu nipa awọn ti o lọ si Ṣọṣi ati awọn ti o lọ si Mọsalasi lọ ṣe isin ti Ṣọṣi ati Mọsalasi na wo pa wọn patapata.

Kinni o wa fa eleyi tabi igbagbọ awọn ni ko to ni tabi Ọlọrun nsọ fun wa wipe kiṣẹ awọn ti o npejọ suru sinu ile kan lasan ti ko si ifẹ ninu wọn ni yio wọ ijọba on Ọlọrun?

Eleyi ko ye mi rara, ṣugbọn ọna Ọlọrun awamọridi ni. Boya o nidi ti o fi npa awọn ti o wa sin in ni Ṣọṣi ati Mọsalasi lati le ma mu wọn kuro ninu wahala aiye, iyẹn ni ko ye mi.

Olotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi yi. Ọlọrun ko ni jẹki ẹ lọ si Ṣọṣi lọjọ ti ile ba fẹ wo.

Emi ni,
Baba Igbagbọ
Esi;
leti Ọffa

### Otito Dara Pupo

Kiloṣe ti awọn oṣelu wa feran lati ma purọ fun wa? ọpọlọpọ igba ni a ma nṣe akiyesi pe awọn oṣelu wa na ko nfẹ sọ otitọ ti o ba wa nidi ọrọ pataki ti o fẹ mọ nkan ijọba.

Boya awọn oṣelu wa yi ti gbagbe wipe ile ti a ba fi tọ mọ iri ni yio woo. Awa ara ilu ti awọn oṣelu yi gbojule paapa kiṣe omugọ rara, awa na ṣẹṣẹ ngbọn, bi ọjọ lati dibo ba de a o ro uri wa wo, a o si mọ iru awọn enia ti a o dibo fun lati ma lọ sile igbimọ)

aṣofin.

O tun wa jẹ aṣa awọn oṣelu wa lati ma hu iwa ẹlẹnu meji, o ko le gbọ ọrọ kan pataki lẹnu wọn lọjọ kan. Iyẹn ni wipe ile igbimọ ni nwọn ti nkọ irọ?

Ẹ jọwọ, ẹ sọrọ na ko ye wa.

Emi ni,
James Ajadi

### Ona Ikorodu Ko Dara

Mo gba fun Dokita obinrin, Irene Ighodaro, ti o mbere lọwọ awọn ọga ṣọla jagunjagun wa wipe kiloṣe ti nwọn ko le ṣe afara si ọna Eko si Abẹokuta ti awọn oni mọto ngba nigbati omi ba ọna jẹ.

Olotu, Emi ti mo nkọ iwe yi si yin ti gba ọna na (ọna Aiyetoro si Abẹokuta) nigbati omi ti ba ọna ti a ngba tẹlẹtẹlẹ jẹ, mo si ri wipe nitotọ ni awọn mọto kabiti kabiti ti o ngba oju ọna na lati bi ọsẹ mẹta wa, ti ba ọna na jẹ.

Ori afara ti Ijọba Ip.nlẹ Aiyetoro ti fowo ara wọn kọ ti fẹrẹ wo nigbati awọn mọto nla nla yi ngba ibẹ. O tilẹ jẹ nkan ti o ya wa lẹnu lati gbọ wipe ọpọlọpọ awọn oṣelu wa l'Eko ko mọ wipe ọna kan wa ti o njẹ ọna Aiyetoro ti a le gba de Abẹokuta ati Ibadan. Ọna na jinna ni, ṣugbọn o dara pupọ ju ọna Ikorodu ti Ijọba Apapọṣẹ nnawo gọbọyi si lọdọdun lọ.

Ẹ ba wa sọ fun awọn alamojuto Ijọba Apapọṣẹ na ki nwọn wa ba wa tun ọna wa ti nwọn bajẹ ṣe.

Emi ni,
Adegoke Akani.
Imasai,
leti Aiyetoro

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

## Ilewe Di Golu

Awọn ti o ba lọ si ilewe ni atijọ yio mọ wipe ile ẹe ti di golu nisisiyi. Ni aiye atijọ gbẹfẹ ni atilọ si ile ẹkọ, awọn Oyinbo Ojiṣẹ Ọlọrun (Missionaries) i nbẹ awọn obi wa lojumọ wipe ki nwọn jẹ ki a wa ko ẹkọ. Boya o fẹ mọ iye ti a nsan ni oṣoṣu nigba na-sisi ti awọn Yoruba npe ni ẹgbaa ni a nsan. Awọn Tiṣa Olukọni paapa nkọ, elo ni owo oṣu ti nwọn ngba? Şile medogun loşu ni nwọn nsan fun wọn.

Ẹniti o ba ri awọn abiyamọ ti nwọn ko awọn ọmọ wọn wa si ilewe lati forukọ silẹ fun ẹkọ ti nwọn fẹ bẹrẹsi ko ninu ọdun ti mbọ, a ki abiyamọ ku wahala. Ọpọlọpọ ni nwọn ti gbọ busun lọ si ibiti awọn ọmọ na ni lati forukọ silẹ; ẹlomi pa ogunlọgọ, ẹwu buba ti ẹlomiran wọ faya. Şe ẹnyin na wa ri iṣẹ abiyamọ bayi! Ọlọrun jẹki a jere wọn.

## Oku Oloye, Owo Ni

Aiye owo ni a wa nisisiyi; bi ọmọde ba fe sọrọ a darukọ owo, bi agba ba lanu a wipe bi on ba ri owo pẹnrẹn, on a dara. OWO WA DI ORISHA ti gbogbo wa nsin lojojumọ. Bi a ba lọ ki awọn ọmọ oloku ni aiye isisiyi, a ko lọ ba wọn kẹdun owohiba ni a ba lọ.

Emi Ayiluka lọ sibi oku Oloye Eko kan lọsẹ ti o koja yi, ẹ jẹ mọ wipe gbogbo awọn ti mo ni ireti wipe ma ba pade nibi oku na kọ ni mo ri. Awọn kan faake kori wipe awọn ko le lọ sibi oku ti awọn ko ni ri nkan pọnla nibẹ.

Mo gbọ wipe olori awọn enia kan ni ẹgbẹruu pọnun (£1,000) ni on nfẹ fun owo itufọ oku Oloye na. Bi irọ ni, bi otitọ ni, emi Ayiluka ko le sọ, şugbọn nko ri ẹnikan nibẹ niuu awọn ọmọlẹhin Olori ti a nsọrọ rẹ yi rara lati wa fun awọn ọmọloku laşẹ lati lu ilu Oloye. Ọrọ gbogbo lori şile

## Yoruba Ko Parapo

Şe mo sọ fun yin wipe ko si ọrọ ninu ẹgbẹ Yoruba Parapọ ti nwọn nkigbe kiri wipe awọn kan fẹ da silẹ? Şe ẹnyin na ti wa ri oju aiye lode wipe awọn Yoruba ko le parapọ mọ a fi ti nwọn ba pẹsẹ pọ ti nwọn npara ọna Ẹnugu ati Eko bi nwọn ba fẹ ri nkan jajẹ ninu ọrọ oşelu.

Ara Ibinni (Binni) lọ, awọn Ondo paapa ni awọn fẹ ba tawọn lọ. Melo ni awọn Yoruba ti a fẹ tun pin ara kelekele? Awa Yoruba ko ti parapọ rara, ẹsẹ nikan ni a si npana ti a fi nja oju-titi ọna moto kiri lojojumọ.

## Baba-Ogba

Mo şeşẹ ri iwe kan gba lati ọdọ awọn kan ti o nka iwe irohin yi ni idalẹ ni, Ọgbẹni ti o kọwe si mi na ni on gbọ wipe awọn dokita nfẹ oju oku, elo ni owo ti nwọn yio ma san fun oju meji ti nwọn ba gba. Ọrẹ mi na ni ọrọ oju ko şe yẹyẹ rara. Lati Ikorodu ni mo ti ri iwe arakunrin mi na gba.

Şe ẹnyin na mọ wipe awọn ara Ikorodu ko nfi ọrọ owo şere rara? Mo gbọ wipe ẹnikan ti nwọn npe ni "BABA - ỌGBA" l'ẹko ba wọn tan iyẹn ni o jẹ ki on na ma bere owo pupọ lọwọ awọn ti nwọn ba fẹ sinku iya ati baba wọn.

Tọbọ yọhọ ni ọrọ BABA ỌGBA ti emi mọ o, şugbọn emi ko mọ BABA — ỌGBA ti ẹ nsọrọ rẹ o!

# Eleti—Ofe D'araba


For Your Safety




MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (E.B.) IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.

— Sub - Distributors —

ARMEL'S TRANSPORT LTD.

BENIN-CITY, ONITSHA, ABA.

# Olopa Mba Bale Toba Awon Egba 'Jagun' Rojo Apania

(O bẹrẹ loju ewe keji)

## Ija Ko Dola

Ẹlẹri yi lati ojọ ti awọnti jẹbi bọ Kotu ni ọdaran balẹ awọn, Sanusi Alaka, ti pe gbogbo ara abule jọ ti o ni nkan ti o ba gba ni awọn yio fun, awọn ko gbọdọ rese awọn Ẹgba kan ninu aba awọn o pasẹ wipe Ẹgba k'Ẹgba ti awọn ba ri ninu awọn ti awọn ti fi igba kan le lọ, ti o ba tun pada wa ki awọn yinbọn fun un; ẹniti ko ba ni ibọn ki o lo ada tabi kunmọ.

Fọlọrunsọ ni ọrọ balẹ awọn na ba on lẹru, on ni ki o m jẹ ki awọn ṣe bẹ rara, awọn ọlọpa wa nilu ti awọn le ko ọrọ na lọ ba.

O ni nṣe ni gbogbo awọn ti o wa lọdọ balẹ na kegbe le on pe ọdala ni on, nwon si le on jade kuro nibẹ nwọn gbe ti nṣe eto ija ti nwọn fẹ ja pẹlu awọn Ẹgba ati awọn nkan ti nwọn yio fi ba wọn ja lọjọ ti nwọn ba foju kan wọn ni abule na,

### Bale Pania

Ẹlẹri yi ni nitotọ lọjọ ti awọn Ẹgba npada bọ si abule awọn, Ọgbẹni kan ti nwọn npe ni Salawu Obilẹyẹ ni o saju wọn lọjọ na, Gbara ti Alaka, balẹ awọn ti ri ibọn olo-ju mẹji rẹ ni o gbe ti o yin pa Ọgbẹni na ni a pa fọn.

Ẹnikẹni ti o tun sọrọ ni Kotu lọjọ na ni Lasisi Amọọ, o ni nigbati on sọ wipe on ko ni lọwọ nina a nfi ibọn tabi ada ba enia ja nṣe ni awọn ara abule awọn dawọ bo on ti nwọn le on sita bi ẹni le aja. O ni ibiti nwọn gbe nti on ni nikuti nwọn ka on lehin oke. Ẹlẹri na ya ẹnu rẹ, o fi ibiti ehin na gbe ti ka han adajọ ni Kotu.

Awọn loya agbẹjọro mẹfa ni awọn ọdaran na gba ninu awọn loya Ibadan. Nwọn ko si ti pari ẹjọ wọn na.

---

### Aja Le Egungun Wole

# Egungun Di Enia

EKO—Egungun sọrọ bi enia, ara ọrun kan di ara araiye ni irọlẹ ọjọ Alaruba (Wednesday, August 21) ni nkan bi agogo marun abọ ni egungun na yọ pẹlu atori ati awọn ọmọ wẹwẹ ti o ko sẹhin, bi egungun na ti njo, ti o sare siwaju sẹhin ni aja kan gbọ ariwo awọn ọmọde ti o wa lẹhin rẹ na.

Aja yi bẹrẹsi pa kuru mọ egungun na, o si ngbo kikan kikan. Atọkun egungun yi fẹsẹ fẹ, awọn ọmọde paapa sa wọle, egungun yi wa bẹsẹsi fọ bayi wipe: "Tani o ni aja yi o? Ẹ kilọ fun aja yi o!! Ẹ ba mi mu aja yi so o!!!"

Bayi ni egungun yi fi style sa wọle kan ti ko si jade mọ titi di alẹ.

---


A Nte Asoju Fun Iwe Irohin Eleti-Ofe

LATI AWON ILU OKE RE


# Oni Wayo

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

nwọn a tọ bi ẹnipe oluwarẹ ṣe orire, o n ami mẹrinlelogun (24pts) ti nwọn nfẹ; nwọn a si fi iwe na ba ara awọn iwe ti awọn ti nwọn ti gba jọ.

Iwe bayi ni a-ṣe-pin-owo (dividends) ti nwọn ntẹ sinu iwe irohin ni ọsẹsẹ kiṣe iwe otitọ- iwe wayo ni. Nwọn ntẹ wọn lati fi fa awọn enia mọra ni. Melo-me'o ni awọn enia ti nwọn ti pa lẹkun nipa iru iwa bayi? Nwọn ko niye rara.

## Awon Olopa..?

Ọgbẹni kan ti o ṣe orire lori pulu ti o ta lọjọ kan sọ nkan ti oju rẹ ri fun mi nigbati o ti ni igbẹkẹle wipe on bọ saiye tuntun fun owo gọbọyi ti on fẹ gba lọwọ awọn onipulu ti on ta lọwọ rẹ. O duro fun ọsẹ kan ko ri owo gba, o kọwe si wọn, nwọn ni ko to iwe pulu (coupno) rẹ daradara. Nwọn ko mọ wipe ki Ọgbẹni yi to fiwe pulu na ranṣẹ si wọn, o ti ya a ni fọto (photostat) lati fi dẹ wọn.

Nwọn fa ọrọ na titi, nigbati nwọn ri wipe ọrọ Ọgbẹni mi na ju ti wọn lọ, nwọn ni ki o dẹ ẹ fun awọn, nwọn si fi owo diẹ rẹ ẹ lẹkun, owo yoku si jẹ apasapo. Ira yẹn pọ pupọ ti nwọn nṣe ni ọọsẹ.

## Iwe Adamodi

Nipa ti iwe pulu orukọ adamọdi ti pọ pupọ ju ti nwọn ntẹ jade. Ki enia ba sebi awọn ti a ti mba ta pulu ni Cardiff, Liverpool ati London ni a mba tayo, awọn baba Oniwayo yi a ma sọ orukọ iṣẹ pulu wọn ni orukọ awọn Oyinbo onipulu nlanla bi ..OPES, ..ERNONS, ..ETTERS, SHERMANS, ...WOODS ati orukọ bẹẹbẹ lati le fi fa awọn enia mọra k. nwọn le [illegible] lẹsọrẹ

Oyinbo ọrẹ mi kan sọ fun mi wipe awọn ara wa ti o nṣe iṣẹ pulu ni ilẹ wa kiṣe iṣẹ wọn ni ọna otitọ rara. O ni on niran igbati awọn alamojuto Ijọba ilẹ wa ko ti paṣẹ wipe ẹnikẹni ko gbọdọ kowo rẹ le pulu ilu Oyinbo mọ, Oyinbo na ni no ko owo gọbọyi le pulu kan in ilu Oyinbo on si je owo ti o jọju, ṣugbọn ọmọ Nigeria kan ti o jẹ aṣoju fun awọn Oyinbo na ti nwọn fi owo ranṣẹ si lati London ko san titi di ọjọ oni.

Iwa re o, ẹnyin ọkawe wa, Oyinbo yi nikan kọ ni baba aṣoju awọn Oyinbo onipulu yi paro, ogunlọgọ awọn enia ni o pa lẹkun, emi OLOFINTOTO alara paapa wa ninu awọn ti nwọn ta, ti nwọn ko ri epinni gba bẹ awọn Oyinbo onipulu kọwe si mi wipe awọn ti fowo mi ranṣẹ sii.

Mo bẹ ẹnyin ọkawe wa ẹ mase fun awọn oniwayo oniṣẹ pulu nwọnyi laye lati jẹki nwọn ri yin ko ni ikokuko. Ẹ ma ṣe akiyesi iwe ipolowo wọn ti yio ma jade lemọlemọ lati ibẹrẹ osu ti a fẹ mu yi, ṣugbọn awọn oniṣẹ pulu diẹ ti nwọn nṣe otitọ, ọdọ wọn ni ki ẹ lọ fowo yin ṣere si.

---


E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe Losose



BE TALLER

Increase your Height. Details free. Add:— C.T. Hospital, Azad Market

Delhi 6, India.

# English Bishop To Advise On Church School Problems In Nigeria

SALFORD. —The Roman Catholic Bishop of Salford, in Lancashire, the Rt. Rev. George Andrew Beck, is paying a two-and-half week visit to Nigeria this month at the invitation of the Roman Catholic Hierarchy in Nigeria.

Bishop Beck, who is a leading authority in Britain on Church school education matters, has been invited to make a special study of the education stistem in Nigeria and to advise on Church school problems; during his visit he will visit schools in all regions.

The Bishop is a member of the Teaching Order of the Augustinians of the Assumption and was for some years headmaster of a Catholic Grammar School at Hitchin, Herfordshire.

He is Chairman of the Catholic Education Council a national assembly which advises on Catholic education matters and is responsible to the Catholic Bishops in Britain.

## Nigerian Choir On British Radio

LONDON — Millions of British radio listeners will hear the choir of St Jude's Church, Ebute-Metta, singing hymns next Sunday, September 1.

The choir will be featured in a five-minute religious programme called "Words and Music" on the B.B.C. Home Service which uses recording of choirs from all over the world.

The record chosen of the St. Jude's choir will be of the hymns 'Remember the Goodnes of the Hold King' and "He will Rejoice".

# New British Film On History Of Football

LONDON—Britain's Football Association, which celebrates its centenary in October, is marking the anniversary with a 25 minute black-and-white film called "Home and Away' which will shortly be shown in sixty-six countries, including Nigeria.

The film deals with the development of football from its earliest amateur origins to its present day international popularity. Made by Associated British Pathe Limited and directed by Sean Graham for the British Government's Central Office of Information, the film is being dubbed in fifteen languages.

The film will be made available for cinema and television screening through the British Information Service.

Football originated in Britain and it has blossomed out into the world's most popular sport.

Today, the Football Association's influence is felt all over the world, with over ninety countries playing the game to common rules which have evolved from those drawn up by the Association 100 years ago.

## Queen Mother To Visit Australia And New Zealand

LONDON-Queen Elizabeth Queen Mother has accepted an invitation from the Government of Australia to visit Australia in March next year, it was announced from Clarence House, London, at the weekend.

During her stay, which will be from three to four weeks, the Queen Mother will perform the opening ceremony of the Third Adelaide Festival of Art of which she is patron, and will also visit Tasmania and Western Australia.

The Queen Mother has also been invited to visit New Zealand. She will spend about two weeks there before going on to Australia.

## Olando Paso Traing For Two Big Fights

LIVERPOOL-Orland Paso former welterweight champion of Nigeria, is training hard at Liverpool for two big fights lined up for him next month.

For the first, at Liverpool Stadium on 12th September, he will box before an audience of millions, for the contest against an opponet still to be named is to be televised in Britain.

Eleven days later, on 23rd September, he is called to fight at Belle Vue, Manchester, and there is a possibility that he will then meet Mickey Leahey, the present British middleweight champion.

Twenty-six-year-old Paso, from Ejirin near Ikorodu, came to Britain five years ago to gain Boxing experience. Now he is managed by Tony Vairo the man who managed world champion Dick Tiger when he was an unknown boxer in Britain,

# African Coffee Interests Safeguarded

LONDON—A Deputy Executive Director who has knowledge and understanding of Africa coffee affairs is to be appointed to the International Coffee Secretariat.

This resolution, prepared by a group of countries including Britain, and Brazil, was approved yesterday, by the Council elected at the International Coffee Conference in London.

The resolution is in two parts, as follows:-

(a) 'The council of the International Coffee Council decides that there shall be a First Deputy Executive Director on the staff who shall also be head of the Department of Economics and Statistics and in the temporary absence of the Executive Director shall perform his functions. He shall be appointed from an adequate list of candidates produced from the African Group of coffee-producing countries and shall include among his qualifications knowledge and understanding of African coffee affairs, and;

(b) Recommends to the Executive Director that in his consultation with the Executive Board for the appointment of heads of departments he shall take into considerations the desirability of assuring the most equitable geographic distribution possible as a supplementary criteria to personal qualifications."

Briggs Pekunso Ninu Igbo:

# Ejo Kola Eleri Sonu Larin ilu Eleyi Ara

(O bere loju ewe kerin)

Eni odun marundinladota ni Briggs ti awon olopa pelu iwawo re nwa kiri yi, on ni akowe ti o ntoju ile epo m to ijoba ni ipinle Ila Orun ni Enugu.

A gbo wipe awon ologpanu ti ri awon akowe kan ti nwon je epo moto ijoba ko mu, nwon si ti tejo won si iwaju adajo ni Kotu lati ba won ro ejo ole ti nwon ji na. Ogbeni ti o sonu yi ni o si ni lati ro eyiti o je pataki ninu ejo na.

Awon ebi Briggs ni o ni lati je wipe awon ti lo paa sinu igbo nibi kan ni, nitoripe nkankan ko see lale ojo ti o jade ati 76, Ogui Road ti o ngbe ni Enugu ti awon ko si ri ki o pada wa sile mo di ojo oni.

Gbogbo awon onisegun ati adahunse ti o mbe ninu Enugu ni iyawo Briggs pelu awon e i re ti gbowo fun wipe ki nwon ba awon wa okunrin ti o sonu na. Omo mi ku ya ju omo mi so nu lo.

## Eleri Na Pekunso

Irohin pajawiri kan ti a ri gba loru ana nipa oro eleri na ni pe awon Olopanu ni Enugu ko sinmi lati ma wa Ogbeni Briggs na kiri gbogbo inu igbo ti o mbe ni ilu Enugu. Nibti nwon gbe nwa kiri na ni nwon ri oku okunrin kan ti o pokunso sinu igbo.

Wara were nwon ti lo pe omo Briggs ti o nse ise ts a ni Port-Harcourt ti o gbaye wa si Enugu nigbati o gbo wipe nwon nwa baba on kiri. Nse ni o bu sekun nigbati o ri baba re lori igi ti o so si ti o nti doro-doro ninu igbo.

Egun ola ni baba ologbe Briggs ti o nje Cyclops Briggs ara Abonema fi sile fun, on nikan ni baba re na bi.

# Ogunpa Se Onile Mole

O bere loju ewe kinni

isale Agbokojo gbogbo iso awon ara Igbajo ti nwon nti pataki ti di odo nla gbogbo patako won ni omi si ngbe lo.

panapona ilu Ibadan lo haya awon oloko oju-omi wipe ki nwon ma lo gbe awon ti omi e nole jade ninu ile wo.

## Omi Gbenia

A gbo wipe omi agbara Ogunpa gbe enia lo, iye awon t o gbe lo ni a ko ie si okunrin kan ti ara re n da ti o ma nsun nibi iso awon elepo moto ni Ogunpa wa ninu awon ti omi na gbe lo ni ijeta losan gangan.

Bi enia ba ri awon Oyinbo Kora onisowo ati awon omo won bi nwon ti r, ti gbogbo eru won baje anu a se oluware, a si ba won kanu. Nse ni awon Ni G se ni ar igbo Kora ka gun petesi ile re lo ti o nsokun wipe ki nwon wa gbe on jade, gbogbo omi ti ya wo iyara ile onje re, ko tile ri Kuku agbonje re mo, ebi ni on ebi.

## Oja Dugbe

Eiye ni a wi, ko si ni Oja Dugbe ti gbogbo enia nna, awon ni nwon gbe moto gba ona Onivanrin ti nwon fe gba dele ni omi ti de titi ti o fi de Ina'ende:

Oja Gegelose nikan lo san die sugbon awon ara Oke Ado ko le koja wa na oja na nitoripe omi ti bo afara iyana Oke Foko; Opolopo awon akowe omi moto ni nwon ko le lo si ibise won ni Agodi.

Opolopo Sosi ati Mosalasi ni omi bo ni ona Sosi awon Salvation Army leti Oke Padi, gbogbo ile ti nwon nta epo moto ni omi agbara na wo patapata. Ko si moto akero kan ti o le wo Ogunpa lati kero.

## Ona Abeokuta

Gbogbo awon ero ti nwon fe gba ona Abeokuta wolu Ibadan ni oju won ri nkan nigbati nwon de ODO ONA, nwon ni lati da gbogbo ol o won duro nitori omi ti ru afara ori odo ni lo patapata nitori eyi nwon ti ona na pa patapata ni o turo ana.

Ona Owo si ilu Benin paapa ti di ona Olomide, afara meji ti ya bomi lo patapata. Gbogbo awon moto ti o nfe wa si Ibadan ni nwon agbe gba Auchi ati Owo-ona ibe loku ti awon ara ilu Benin ati Onitsha ngba.

Oko Reluwe ti o nko ero lo si Kano ti pada ni Olokemeji nitori omi ti o ba ona je, ni Tesan Adio ati Ibomiran. Eyiti mbo lati Kano duro ni Ibadan. Ni ana, awon ara Ibadan ko ri iwe irohin ti a ko ranse si won lati Eko gba, boya nwon sese te won lowo loni ni. Nkan nkan ni Ibadan nisisiyi.

# Mosalasi Jimo Ilu Eko Goke Agba

EKO—Ni ola ojo Abameta (Saturday) ni awon janma ilu Eko fe se nebe Masalasi Jimo ti o di adota odun ti nwon ti ko Mosalasi na ati pe nwon tun nfe owo iranlowo lodo gbogbo awon janmo Musulumi ilu Eko fun ose med gbon poun (£500,000) ti nwon ni nwon tun fe na lori afikun ile Mosalasi na.

Ni agogo merin oni ni nwon yio beresi se ajoyo odun Jubili na ninu Mosalasi na l'Ehinogba. Olola Abubukar Tafawa Balewa, Olotu Ijoba Apapose ni yio si eto oro owo iranlowo ti awon janmo se wipe awon nfe na Ogunlogo enia ni awon ti fiwe pe sibi aseye ti oni na.

Awon die ti a le daruko niyi ninu awon igbimo eto ile Mosalasi kiko na, awon ni Alhaji Elias (alaga), Ogbeni M. Giwa Salvador, akowe won ti o se opolopo wahala lati ri wipe eto-aseye na lo daradara, Ogbeni Onikoyi, akapo, Alhaji A.Y. Ojikutu, M.M.A. Umar Isiaka Animashaun, Alhaji Ali-Balogun ati Alhaji Sogunro. E ku aseye na.

E ka oro OLOFINTOTO Eleti-Ofe

ati awon Oniwayo (Pools) loju ewe keta iwe yi. OLOFINTOTO ti tuna asiri won. Eleti—Ofe d'araba e ma ka a nigbagbogbo.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor: (Olotu) Ola Onatade, 15,Kosoko Street, Lagos, Box 467